Dajudaju ẹ maa ri Oluwa yin gẹgẹ bi ẹ ṣe n ri òṣùpá yìí, ẹ o nii ri inira nibi riri rẹ

Lati ọdọ Jeriir ọmọ Abdullahi- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: A wa lọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, o wa wo òṣùpá ni alẹ ọjọ kan- o n túmọ si òṣùpá ọjọ kẹrinla- o wa sọ pe: "Dajudaju ẹ maa ri Oluwa yin gẹgẹ bi ẹ ṣe n ri òṣùpá yìí, ẹ o nii ri inira nibi riri rẹ, ti ẹ ba ni ikapa ki wọn maa kọdi yin kuro nibi irun ṣíwájú yiyọ oorun ati ṣíwájú wiwọ rẹ, ki ẹ yaa ṣe bẹẹ" lẹyin naa o ka:"(Kí o sì ṣe àfọ̀mọ́ pẹ̀lú ìdúpẹ́ fún Olúwa Rẹ ṣíwájú yíyọ òòrùn àti wíwọ̀ (rẹ̀).)"

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Awọn saabe wa pẹlu Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni alẹ ọjọ kan, o wa wo òṣùpá- ni ale ọjọ kẹrinla-, o wa sọ pe: Dajudaju awọn olugbagbọ maa ri Oluwa wọn ni ti paapaa pẹlu oju laisi iruju, ati pe wọn ko nii fún papọ mọ́ra wọn, wahala tabi inira ko nii ṣẹlẹ si wọn nibi riri Rẹ- Ọba ti ọla Rẹ ga-. Lẹyin naa, ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: Ti ẹ ba ni ikapa lati ge awọn okunfa ti o le yi yin kuro nibi irun asunbaa ati irun Asr, ki ẹ yaa ṣe bẹẹ, ki ẹ si mu mejeeji wa ni pipe ni asiko mejeeji ni janmọọn, dajudaju ìyẹn wa ninu awọn okunfa wiwo oju Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn, Lẹyin naa, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa ka aaya naa: (Wa sabbih bihamdi Robbika qobla tuluu'ish shamsi wa qoblal guruub)

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5657

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee